UK Health Security Agency



# Itọsọna kan lori ajẹsara COVOD-19 fun awọn obinrin to loyun tabi nfọmọ lọyan

**Awọn Kọlẹji Royal ti awọn Olutọju Alaboyun ati Oníwòsàn tí ntọ́jú abowún ati Kọlẹji Royal ti awọn Agbẹ̀bí ti d’amọran ajẹsara COVID-19 fun awọn obinrin to loyun ati awọn tó nfọmọ lọyan. Abẹrẹ ajẹsara aarun corona (COVID-19) to wa ni UK lo ni aabo to si peye julọ.**

## Imọran Abẹrẹ ajẹsara COVID-19 ninu Oyun

Imọran Apapọ Igbimọ lori Abẹrẹ Ajẹsara ati Eto Ajẹsara (Joint Committee on Vaccination and Immunisation (JCVI)) ni wipe awọn obinrin to l’oyun wa ni ewu lile aarun COVID-19. Àfikún abẹ́rẹ́ àjẹsára ti ìgbà ìrẹ̀dànù ní a ó fún àwọn tóní àwọn ewu ìdíjú àkọ́ràn COVID-19 gíga, tó le má tíì gba àfikún fún àwọn osù díẹ̀. Eyi pẹlu awọn obinrin alaboyun. Bí iye àwọn àkọ́ràn COVID-19 ṣé ńpọ̀ sìi ní àkókò òtútù, àfikún abẹ́rẹ́ àjẹsára yìí gbọdọ̀ ṣe ìrànlọ́wọ́ láti dín ewu ìgbàsílẹ̀ sí ilé-ìwòsàn pẹ̀lú COVID-19. Àfikún abẹ́rẹ́ àjẹsára le pèsè àwọn ààbò kọ̀ọ̀kan tako àkóràn Omicron tí kò le sùgbọ́n irú ààbò bẹ́ẹ̀ kìí pẹ́ rárá.

A fún ọ ni abẹrẹ ajẹsara naa lati daabobo iwọ ati ọmọ rẹ. Ni UK, iye obinrin to ju 250,000 lọ lo ti gba abẹrẹ ajẹsara saaju ti wọn to bimọ, pẹlu abẹrẹ ajẹsara Pfizer ati Moderna.

Awọn abẹrẹ ajẹsara wọnyi ni akọsilẹ aabo to dara ninu awọn obinrin to loyun ati awọn ọmọ wọn. Abẹrẹ ajẹsara COVID-19 ko ni ààyè ààrùn corona ati wipe ko le ran alaboyun obinrin tabi ọmọ inu rẹ ti kò tii bi.

Ẹri lori abẹrẹ ajẹsara COVID-19 la ti n ṣe ayẹwo rẹ ni siṣẹntẹle nipa Ajọ Ilera Agbaye (World Health Organization) ati awọn igbimọ ti nsamojuto ni UK, Amẹrika, Canada ati Europe.

Abẹrẹ ajẹsara COVID-19 jẹ ọna to ya to si munadoko julẹ fun awọn obinrin lati daabobo ara wọn ati awọn ọmọ wọn tako aarun COVID-19 lile. A gba awọn obinrin ti ko gba abẹrẹ ajẹsara ti o loyun niyanju gidigidi lati wa fun abẹrẹ ajẹsara wọn.

**Awọn obinrin to loyun  ti wọn si ti gba abẹrẹ ajẹsara tẹlẹ gbọdọ gba alekun abẹrẹ ni ìgbà ìrẹ̀dànù yii.**

O le ri iwifun siwaju sii ni **Oyun, Ifọmọ lọyan ati Abẹrẹ Ajẹsara COVID-19**

## Kini idi ti o fi nilo abẹrẹ ajẹsara bi o ba loyun

Bi o ba ni aarun COVID-19 lasiko iloyun rẹ, iwọ ati ọmọ inu rẹ wa ninu ewu aarun to ga to nilo itọju ile-iwosan, ati iranlọwọ itọju to ga.

Apapọ ewu lati ọdọ aarun COVID-19 fun iwọ ati ọmọ tuntun rẹ lọlẹ sugbọn ti lọ soke ni ọwọja COVID-19 to yatọ. Aaye ikoran le yatọ kiakia pelu a si lero pe o le lọ soke ni akoko otutu.


Awọn abẹrẹ ajẹsara COVID-19 fun ọ ni awọn ipele aabo tako aarun sugbọn ipele aabo nlọlẹ pelu akoko. Koda bi o ba ti gba abẹrẹ ajẹsara COVID-19 tabi ni aarun, alekun abẹrẹ ajẹsara naa ṣe pataki lati ṣe iranlọwọ aabo fun iwọ ati ọmọ rẹni akoko awọn osu otutu to n bọ nigbati a n reti ki ipele aarun ko lọ soke.

Iwifun idaniloju lori aabo awọn abẹrẹ ajẹsara COVID-a9 ti a fun awọn obinrin to loyun ni UK, nibiti ju iye obibrin 250,000 lo ti gba abẹrẹ ajẹsara saaju ibimọ, ati ni ọpọ orilẹ-ede ti US ati Australia naa pẹlu.

## Awọn ewu fun awọn obinrin to loyun

Bi o ba ni ipo aisan ilera kankan bii:

- awọn isoro  idasilẹ ailera
- Ikọ ife
- Ẹjẹ riru
- aarun ọkan
- Ìtọ̀ súgà



**Tabi bi o ba ni:**

- Sisanra ju
- ọjọ-ori 35 lọ
- ni ipele oyun kẹta (ju ọsẹ 28 lọ)
- ti ipilẹ asa awọn alawọ dudu ati Asia ti ko wọpọ
- Ni ko tii gba abẹrẹ ajẹsara tabi ti gba abẹrẹ ajẹsara ni ààbọ̀.

**O wa ni ewu COVID_19 sii ju awọn obinrin pẹlu ọjọ ori kanna ti wọn ko loyun** Awọn obinrin oloyun pẹlu awọn ailera wa ni ewu isoro awọn idiju giga lati ọwọ COVID-19.

## Àkókò àfikún abẹ́rẹ́ àjẹsára ìgbà ìrẹ̀dànù

O gbọdọ̀ gba àkókò ìpàdé kan láàrin osù Kẹsan àti Ìkejìlá, tí á ó sì kọ́kọ́ pe àwọn tóní ewu gíga wọlé.

**O gbọdọ̀ gba àfikún abẹ́rẹ́ àjẹsára ní ó kéèré tán osù 3 lẹ́yìn ìgbàtí o gba abẹ́rẹ́ àjẹsára tó gbẹ̀yìn.**

O le gba abẹrẹ ajẹsara ọfinkin ni igba kanna. O ṣe pataki pe ki o daabobo ara rẹ ni akoko oyun lati daabobo iwọ ati ọmọ rẹ. Maṣe duro di igba ti o ba bimọ.



## Bi o ba loyun

Awọn ewu aarun COVID-19 fun awọn obinrin oloyun ati awọn ọmọ inu wọn ati bi o ṣe rọrun lati ni aarun naa ti yatọ pẹlu orisirisi iru COVID-19 to wa. O ko le sọ orisii tuntun ti yoo jade, nitorinaa o ṣe pataki lati rii pe o ni aabo to peye bi o ba loyun. Ẹri wa wipe ajẹsara ninu oyun le ṣe iranlọwọ lati dena gbigba awọn ọmọ ọwọ ni osu mẹfa akọkọ aye wọn silẹ ni ile iwosan latari COVID-19. Eyi ribẹ nitoripe idasilẹ ailera ninu iya le waye lori ọmọ ninu ile ọmọ ey si ma npese aabo ọlọjọ kukuru lẹyin ibimọ.

Awọn obinrin ti wọn loyun ni a ko si abẹ ipin ewu iṣegun laarin eto gbigba abẹrẹ ajẹsara COVID-19. Awọn obinrin ti ko tii gba abẹrẹ ajẹsara ti wọn loyun ni a ti gba niyanju gidigidi lati gba abẹrẹ meji akọkọ ajẹsara naa.
Awọn obinrin to loyun  ti wọn si ti gba abẹrẹ ajẹsara tẹlẹ gbọdọ gba alekun abẹrẹ ni ìgbà ìrẹ̀dànù yii.

## Nini Oyun

Kosi idi lati yago fun nini oyun lẹyin abẹrẹ ajẹsara COVID-19. Irisirisi iwadii ijinlẹ sayẹnsi ti fihan wipe abẹrẹ ajẹsara COVID-19 ko ni ipa lori ibimọ ọkunrin ati obinrin, awọn anfaani lati ni oyun tabi lori ewu iṣẹnu obinrin. Bii awọn obinrin 100,000 ni England ti gba abẹrẹ ajẹsara COVID-19 saaju ki wọn to loyun ti wọn si lọ ni ọmọ wọn.

## Ifọmọlọyan

A mọ awọn anfaani ifọmọlọyan daradara.

Awọn JCVI ti damọran wipe a le gba awọn abẹrẹ ajẹsara naa lasiko ifọmọlọyan. Eyi wa ni ibaamu pẹlu awọn aba imọran lati Amẹrika ati Ajọ Ilera Agbaye. Awọn obinrin to ti gba abẹrẹ ajẹsara pese awọn ajẹsara ti yoo daabobo wọn tako aarun COVID-19. Awọn ajẹsara wọnyi ni a ti ri ninu miliki ọyan pẹlu o si le ṣe iranwọ lati daabobo awọn ọmọ to nmu ọya. Abẹrẹ ajẹsara gangan kii bọ sinu miliki ọyan.

## Abẹ́rẹ́ àjẹsára wo ni o máa gbà?

A ó fún ọ ní àfikún abẹ́rẹ́ àjẹsára tí Pfizer tabi Moderna ṣe. O le gba apapọ iru awọn aleku abẹrẹ ajẹsara tuntun wọnyi - apapọ abẹrẹ ajẹsara naa ni idaji abẹrẹ ajẹsara ti tẹlẹ pọ mọ idaji abẹrẹ ajẹsara tako iru ajẹsara Omicron. Fún iye àwọn ènìyàn to kéére dókítà rẹ le d'ámọ̀ràn ọjà abẹ́rẹ́ àjẹsára mìíràn fún ọ.

Àfikún abẹ́rẹ́ àjẹsára àti àpapọ̀ àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára ńmí kí ààbò gbèrú sí dáradára, bíótilẹ̀jẹ̀pé àpapọ̀ àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára náà ńpèsè àwọn àjẹsára ní ìpele gíga díẹ̀ tako àwọn ọwọ́jà Omicron.

Gẹ́gẹ́bí a kò ti le sọ irú àwọn ìyàtọ̀ COVID-19 tí yóò ma ràn káàkiri àkókò òtútù yìí, Ìgbìmọ̀ Àpapọ̀ lórí Gbigba Abẹ́rẹ́ Àjẹsára àti Abẹ́rẹ́ Àjẹsára (JCVI) ti fẹnukò pé irú àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára méjèèjì jẹ́ lílò fún àwọn àgbà, àti wípé kòsí ẹnikẹ́ni tó gbọ́dọ̀ dá gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára dúró láti gba àpapọ̀ àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára. Nígbànáà a ó fún ọ ni abẹ́rẹ́ àjẹsára tó yẹ ní àkókò tó yẹ.

Jọ̀wọ́ gba abẹ́rẹ́ àjẹsára tí a bá fún ọ ní kíákíá bí ó ti seéṣe fún ọ - o ṣe pàtàkì láti ní àfikún abẹ́rẹ́ àjẹsára tìrẹ àtipé kí o gbé ààbò rẹ sókè tako àìsàn líle sáájú àkókò òtútù.

## Awọn abẹrẹ ajẹsara yooku ti a nfunni ninu oyun

Awọn abẹrẹ ajẹsara lati daabobo iwọ ati ọmọ rẹ tako ọfinkin ati lati dabobo ọmọ rẹ tako pertussis (ikọ lile) lati ibimọ ni daba ni akoko oyun. Awọn orisirisi abẹrẹ ajẹsara wọnyi ni a le rọra funni papọ tabi funni lọtọọtọ yoo si tun pese aabo.

Ọfinkin rẹ ati abẹrẹ ajẹsara COVID-19 ni a le funni papọ gẹgẹbi a ti funni ni akoko ọdun kanna ni eyikeyi ipele oyun.

O ṣe pataki lati gba abẹrẹ ajẹsara pertussis lẹyin ti o ti de ọsẹ 16 iloyun  lati rii daju pe ọmọ rẹ ni awọn ipele aabo giga nigbati o ba bi wọn. A ma nsaba funni ni abẹrẹ ajẹsara lẹyin isayẹwo lẹyin ọsẹ 18 si 20 iloyin ati ki o le gba ajẹsara yii ni orisirisi ipade, latari igbati o ba loyun.

## Ǹjẹ́ o le sì le ní COVID-19 lẹ́yìn gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára?

Àfikún abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 yóò dín ààyè níní àìsàn líle kù láti ọ̀dọ̀ COVID-19 ní àkókò òtútù yìí. Ó le lo àwọn ọjọ́ díẹ̀ kí ara rẹ tó ní àwọn àfikún ààbò láti ọ̀dọ àfikún abẹ́rẹ́ àjẹsára.

Bíi gbogbo òògùn, kòsí abẹ́rẹ́ àjẹsára tó péye pátápátá - àwọn ènìyàn kọọkan le ní COVID-19 kọ́dà bí wọ́n ṣe gba abẹ́rẹ́ àjẹsára tó, sùgbọ́n àrànmọ́ kankan kò gbọ́dọ̀ le.

Gẹgẹbi o ti gba abẹrẹ ajẹsara awọn nkan to rọrun wa ti o le ṣe ni joojumọ aye rẹ ti yoo ran ọ lọwọ lati din itanka COVID-19 kù ati awọn aranmọ eemi ti yoo si daabobo awọn to ni ewu giga. Fún iwifun siwaju sii wo **ìmọ̀ràn NHS**.



## Àwọn ìdíjú

Bíi gbogbo oogun, abẹrẹ ajẹsara le fa awọn idiju to wọpọ. Awọn idiju abẹrẹ ajẹsara COVID-19 jọ ara wọn ninu awọn obinrin to loyun ati awọn ti ko loyun. Kosi awọn ewu pato kan ti a damọ fun awọn obinrin oloyun, awọn oyun wọn tabi ọmọ wọn. O ti jẹ iranlọwọ lati rii daju wipe o mọ ohun ti o nreti lẹyin ti o ti gba abẹrẹ ajẹsara, paapaa julọ bi o ba ni ọmọ rẹ tabi ni awọn ọmọ miiran lati mojuto.

Jọwọ ka **abẹrẹ ajẹsara COVID-19: ohun to yẹ kẹ reti lẹyin abẹrẹ ajẹsara**

### Àwọn ìdíjú tó wọ́pọ̀:

Gẹ́gẹ́bí abẹ́rẹ́ tó ti gbà sẹ́yìn, àwọn ìdíjú tó wọ́pọ̀ papọ̀ mọ́ ti gbogbo abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID_19, pẹ̀lú àwọn àpapọ̀ abẹ́rẹ́ àjẹsára tí a lò ní àkókò òtútù yìí, tí ó pẹ̀lú:

- níní ìnira kan, ìmọ̀lára ara wíwo àti ara rírọ̀ ní apá níbití o ti gba àbẹ́rẹ́ - èyí le ṣeése kó burú tó bíi ọjọ́ 1 sí 2 lẹ̀yìn abẹ́rẹ́ àjẹsára náà
- ìmọ̀lára rírẹ̀
- orí fífọ́
- ara ríro gbogbogbo tàbí ààmì àìsàn ọ̀fìnkìn tí kò le

O le sinmi kí o sì lo òògùn paracetamol (tẹ̀lé ìmọ̀ràn abẹ́rẹ́ nínú àpamọ́ náà) láti ràn ọ́ lọ́wọ́ kí o gbádùn dáradára.

Bíótilẹ̀jẹpé ibà kan le jẹyọ láàrin ọjọ́ kan tàbí méjì gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára, bí o bá ní àwọn ààmì àìsàn COVID-19 mìíràn kankan tàbí ibà rẹ pẹ́, dúró sí ilé àtipé o le nílò láti ṣe àyẹ̀wò kan. Àwọn ààmì àìsàn tó ńtẹ̀lé gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára kìí pẹ́ tó ọ̀sẹ̀ kan.

Bí àwọn ààmì àìsàn rẹ bá fẹ́ burú tàbí bí àyà bá ńfò ọ́, o le pe NHS 111 tàbí fún àtẹ̀jíṣẹ́ lo 18001 111. Bakannaa, o le jábọ̀ àwọn ìdíjú abẹ́rẹ́ àjẹsára àti òògun tí o furasí nípasẹ̀ Ètò Yellow Card.

### Jíjábọ̀ àwọn ìdíjú

O le jabọ awọn idiju ti o ba furasi sí Yellow Card scheme:

- lori ayelujara ni **Yellow Card scheme**
- nípa pípe Yellow Card scheme lórí 0800 731 6789 (agogo 9 òwúrọ̀ – 5 ìrọ̀lẹ́),
- gbígbà sílẹ̀ ati lilo ààpù Yellow Card fún Apple tàbí Android

### Àwọn ìdíjú to le

Àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ọkàn wíwú (tí à ńpè ní myocarditis àbí pericarditis) ni wọ́n ti jábọ̀ níwọ̀nba lẹ́yìn irú àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 Pfizer àti Moderna. Àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ wọ̀nyí ni a ti ń sábà rí nínú àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin àti láàrin ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọjọ́ gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn tó sẹlẹ̀ sì ti ṣe dáradára wọ́n sì ti gbádùn kíákíá ní àyọrísí ìsinmi àti àwọn ìtọ́jú pẹ̀pẹ́pẹ̀ẹ́.

O gbọ́dọ̀ wá ìmọ̀ràn ìlera ní kíákíá bí, lẹ́yìn gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára, o bá ní ìrírí:

- ìrora àyà
- èémí kúkúrú
- ìmọ̀lára níní yíyáralu ọkàn, àìfọkànbalẹ̀ tàbí ọkan lílù pìpì


Bí o bá ní àwọn ìdíjú líle lẹ́yìn abẹ́rẹ́ àjẹsára tó gbà sẹ́yìn a le gbà ọ́ nímọ̀ràn pé kí o yàgò fún tàbí dá gbígbà abẹ́rẹ́ àjẹsára mìíràn. O gbọ́dọ̀ jíròrò èyí pẹ̀lú dókítà tàbí akọ́ṣẹ́mọ́ṣẹ́ rẹ. Jọwọ wo isalẹ fun iwifun lori bi o ṣe jabọ awọn idiju.

### Ìwífún síwájú síi

Awọn Olutọju Alaboyun ati Oníwòsàn tí ntọ́jú abowún (RCOG) ati Kọleji Royal ti awọn Agbẹ̀bí (RCM) ni awọn iwifun miiran ti o le ri pe o wulo lori abẹrẹ ajẹsara COVID-19 **ati oyun**.

Iwifun Iloyun, Ifọmọlọyan, Atile-bimọ ati abẹrẹ ajẹsara COVID-19 lori **NHS UK**.

Bi o ba fẹ lati jiroro gbigba abẹrẹ ajẹsara COVID-19 jọwọ kansi agbẹbi, dokita, tabi nọọsi rẹ.



© Crown copyright 2022. Product code: C22W7YOR Yoruba. 1p 100K SEP 2022 (APS). UK Health Security Agency gateway number: 2022452.
Láti gba ọ̀pọ̀ ẹ̀dà ìwé pélébé yìí jọ̀wọ́ ṣe àbẹ̀wò sí: www.healthpublications.gov.uk tàbí pe 0300 123 1002 nípa lílo kóòdù ọjà: C22W7YOR
Tí a ti mú dójú ìwọn 29.09.2022